# IGBESI-AYÉ ONIGBAGBỌ́

**Romu 12:1-21; 2 Peteru 1:5-11**

**ẸKỌ 357 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ẹ mã takéte si ohun ti iṣe buburu; ẹ faramọ́ ohun ti iṣe rere" (Romu 12:9).**

**Mímọ́**

Jesu gbadura fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ati fun gbogbo awọn ti yoo tẹle E. O gbadura pe ki wọn le jẹ ọ̀kan, ki wọn wà ni iṣọkan pẹlu ara wọn ati pẹlu Ọlọrun. O gbadura pe ki a sọ wọ́n di mimọ́. Isọdimimọ́ ni wiwà ni mimọ́, ki a wẹ̀ wá nù kuro ninu ẹ̀ṣẹ. A fi isọdimimọ́ wé fifa gbongbo igi tu kuro ninu ilẹ. A fi Igbala wé igi ti a ge lulẹ eyi ti kukute rẹ̀ tun le hù ki o si dagba. Ṣugbọn ni akoko Isọdimimọ a fa gbongbo rẹ̀ tu kuro ninu ilẹ.

Jesu gbadura pe ki awọn ọmọ-ẹyin Oun le jẹ́ oloootọ, ati ki wọn le jẹ oloootọ si Ọlọrun, ani ninu ayé ti o kún fún idanwo ati ipọnju. (Ka Johannu 17:15-21).

Isọdi mimọ́ maa n fun Onigbagbọ́ ni agbara si i lati bori ẹ̀ṣẹ. O jẹ "ifẹ Ọlọrun, ani wiwà ni mimọ́ nyin" (1 Tẹssalonika 4:3). Awọn Onigbagbọ́ n fẹ gbé igbesi-ayé ti o bá ifẹ Ọlọrun mu, nitori naa wọn n fi ara wọn rubọ wọn a si gbadura titi Ọlọrun maa fi sọ wọn di mimọ́. Awọn nnkan miiran wà ti Onigbagbọ́ nilati ṣe ki o to le jẹ oloootọ si Ọlọrun, ki o to le ṣe ifẹ Rẹ̀, ati ki o to le wulo fun Un. Onigbagbọ́ nilati ṣiṣẹ ninu isin Rẹ̀, ki o si sa ipa rẹ̀ nigba gbogbo lati jọ Oluwa rẹ̀.

**Apẹẹrẹ**

Ninu iwe rẹ̀ si ijọ ti o wà ni Romu, Paulu darukọ awọn ohun ti o le ràn wọn lọwọ lati le jẹ́ Onigbagbọ́ ti o peye. A le pe awọn ohun naa ni iṣẹ Onigbagbọ́. Wọn jẹ́ apẹẹrẹ fun igbesi-ayé Onigbagbọ́. Nigba ti eniyan ba ni ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn rẹ̀ yoo ka gbigbe igbesi-ayé mimọ́ si anfaani. Yoo fẹ gbe igbesi-ayé ti o wu Ọlọrun, ati ni ṣiṣe bẹẹ oun yoo mọ̀ pe oun wà ni imurasilẹ lati lọ si Ọrun.

Awọn ọmọde miiran mọ̀ pe lati ni ipa ninu ṣiṣe awọn aré kan, tabi lilọ si ibikan, tabi bibá irú awọn ọmọde kan ṣire pọ̀, maa n saba fi wọn sinu wahala. Njẹ kò ni ṣanfaani lati yẹra kuro ninu awọn ohun wọnni ati lọdọ awọn wọnni ti o n mu wahala dani? Bẹẹ gẹgẹ ni o ri fun Onigbagbọ́: nipa yiyà fun ẹ̀ṣẹ, ni gbigba adura ati ni wiwà fun Ọlọrun, oun yoo ni iranwọ lati lè bọ́ kuro ninu wahala.

**Ẹbọ Ààyè**

Paulu n rọ awọn Onigbagbọ́ lati ya ara wọn si mimọ́ fun Ọlọrun, ati ki wọn fi ara wọn fun Ọlọrun ni "ẹbọ ãye". Ni igba lailai awọn eniyan maa n sin Ọlọrun nipa fifi ẹran ti a pa rubọ, ṣugbọn lọjọ oni Ọlọrun n fẹ́ ki wiwà wa maa fi ogo ati iyin fun Oun. Wolii Isaiah wi pe: "Nitori iboji kò le yin ọ, ikú kò le fiyin fun ọ: … Alãye, alãyè, on ni yio yin ọ, bi mo ti nṣe loni yi" (Isaiah 38;18, 19).

Ẹbọ ni ohun ti a fi rubọ, ti a jọwọ rẹ̀ lọwọ lọ, ati ti a yọọda rẹ̀ fun Ọlọrun. Jijọwọ ara ati igbesi-aye eniyan fun Ọlọrun ni "ẹbọ ãye" jẹ jijọwọ ati yiyọọda igbesi-ayé rẹ̀ fun Ọlọrun ati ifẹ Rẹ̀. Ki i ṣe ẹbọ aaye nìkan ni Ọlọrun n fẹ́, ṣugbọn O n fẹ igbesi-ayé mimọ́, ti o bọ́ lọwọ ẹ̀ṣẹ.

**Ipá**

Bawo ni o ṣe le wa ni idominira kuro ninu ẹ̀ṣẹ titi? "Lati di titun ni iro-inu nyin." Paulu sọ irú awọn ọ̀rọ bayii ninu adura rẹ̀ si ijọ Efesu: "Ki a le fi agbara rẹ̀ mú nyin li okun nipa Ẹmi rẹ̀ niti ẹni inu; … ki a le fi gbogbo ẹ̀kún Ọlọrun kun nyin" (Efesu 3:16-19). Ni gbigba adura loroowurọ ṣiwaju lilọ si ile-iwe, ere-ṣiṣe, ati iṣẹ-ṣiṣe, ati nipa kika Bibeli tabi titẹ́ eti silẹ nigba ti a ba n ka a, awọn ọmọde le ni Oluwa pẹlu wọn, Oun yoo le fi hàn wọ́n bi wọn ti le ṣe rere ati bi wọn ṣe le wà fun Un. Kikọ́ awọn ẹkọ Ile-ẹ̀kọ́ Ọjọ Isinmi ati kikọ́ awọn ẹsẹ akọsori wa sori maa n jẹ ki a di titun ninu ero-inu ati alagbara ninu Oluwa.

**Iwa wa si Ẹlomiran**

Ọmọ-lẹyin Oluwa jẹ onirẹlẹ, ẹni ti o n rò nipa ti ọmọnikeji rẹ̀ ṣaaju ti oun tikararẹ̀. Eleyii n hàn ninu igbesi-ayé ti eniyan n gbé lojojumọ́. A le fun ọ làaye lati mú ọ̀kan ninu eso meji, ninu eyi ti ọ̀kan tobi ju ekeji. Satani le sọ̀rọ si ọ leti kẹlẹkẹlẹ pe ki o mu eyi ti o tobi ni nitori pe ebi n pa ọ. Ṣugbọn iwọ yoo ranti pe Jesu kò fẹ ki a jẹ onmọ-tara-ẹni-nikan, ati ki a kọkọ maa rò nipa ti ọmọnikeji ẹni, iwọ yoo fi eso ti o tobi ju silẹ fun ẹnikeji. Eyi jẹ ọ̀na kan ti a le gba fi ifẹ han ati "niti ọlá, ẹ mã fi ẹnikeji nyin ṣaju," lai rò nipa ara wa ju bi o ti yẹ.

**Rere tabi buburu**

“Ẹ mã takéte si ohun ti iṣe buburu; ẹ faramọ́ ohun ti iṣe rere.” Onigbagbọ́ a maa korira awọn ohun buburu, a si takéte si wọn. O fẹran awọn ohun rere a si maa faramọ wọn. Ni akoko ere, ọmọde ti o ba fẹran Oluwa yoo yẹra fun awọn ohun ti o mu ẹ̀ṣẹ dani. Oun kò gbọdọ daba fifi ibọn-ṣireṣire dẹruba eniyan lati ja a ni ole tabi lati pa a. Oun kò gbọdọ ṣafarawe awọn wọnni ti n mu tábà tabi awọn wọnni ti nkun ète, bi o tilẹ jẹ pe iwe kiká lasan ni o fi ṣe taba tabi fifi ẹfun lasan kun ète. Ọmọde Onigbagbọ́ ki i kan saara si iwa buburu ti o wà ni igbesi-ayé awọn wọnni ti o n jale ti wọn si n rẹnijẹ. Satani ni ọ̀na ẹ̀wẹ́ ti o n fi tan eniyan lati rò pe iwa ibi “kò buru tobẹẹ,” a si maa tan wọn lati maa fi ọgbọ́n ẹwẹ ṣe awọn ohun ti kò dara. Paulu ni, “Ẹ mã pèse ohun ti o tọ́ niwaju gbogbo enia.” Niti pe awọn miiran kò gbé igbesi-ayé ti o wu Ọlọrun, kò fun wa ni anfaani lati ṣe ohun kan ti ki yoo dùn mọ́ Ọlọrun ninu.

**Rere dipo Buburu**

Dipo fifi buburu san buburu, Onigbagbọ́ a maa fi rere ṣẹgun buburu. A maa ṣoore fun awọn ti o n ṣe e ni ibi. Oun ki yoo ni ẹmi “igbẹsan.” Oun a maa wá àye lati ṣe oore fun awọn wọnni ti o ti huwa aitọ́ si i. Ninu Iwe Owe a ka nipa ileri ti o wà fun awọn wọnni ti o n ṣoore ati ti o n yọnu si awọn ti o ti ṣe wọn ni ibi. “Bi ebi ba npa ọta rẹ, fun u li onjẹ: bi ongbẹ ba si gbẹ ẹ, fun u li ohun mimu. Nitoriti iwọ o kó ẹyin iná jọ si ori rẹ̀, Oluwa yio san fun ọ” (Owe 25:21, 22). O ha tọ́ ki a ṣe rere si awọn ti n fi wa ṣe ẹlẹya? Bẹẹni, o tọ́. “Ẹ mã súre fun awọn ti nṣe inunibini si nyin.”

**Idàgbà**

O jẹ iṣẹ-isin ti o tọna si Ọlọrun pe ki a wà fun Un. Ọlọrun ki i beere ju ohun ti awọn eniyan Rẹ̀ le ṣe lọwọ wọn. Ki i ṣe kiki pe Ọlọrun ni awọn ohun ti O n fẹ lati ọwọ́ awọn eniyan Rẹ̀ nikan ṣugbọn bẹẹ gẹgẹ O ni iranwọ fún wọn. Ninu iranlọwọ ti O n fi fun awọn eniyan Rẹ̀ ni ifẹ Ọlọrun, ore-ọfẹ, igbagbọ́, ireti, agbara, ati suuru. Awa ni wọn wà fun a si le ri wọn gbà nipa adura ati lati inu Bibeli ti i ṣe Ọrọ Ọlọrun. Eniyan kò le ṣe ohun ti Ọlọrun n fẹ́ laisi iranwọ Ọlọrun.

Nigba ti eniyan ba kọkọ ri igbala yoo ni awọn ẹbun oore-ọfẹ Onigbagbọ́ wọnyii lọpọ tabi niwọn diẹ. Ọlọrun n fẹ ki a dagba ninu awọn nnkan wọnyii. Ninu 2 Peteru 1:5-11 a gbà wa niyanju lati dagba ati lati ni kún eyi ti a ni, ki a ma ba já Ọlọrun tilẹ. Peteru tun kọwe pe ki “ẹ mã dàgba ninu ore-ọfẹ, ati ninu imọ Oluwa ati Olugbala wa Jesu Kristi” ki a ma baa ṣubu kuro ninu iduro-ṣinṣin ati ijolootọ wa (2 Peteru 3:18).

Nigba ti ọmọde kò ba dagba soke mọ ati ti kò tẹwọ́n ju bi o ti wà tẹlẹri, a ma n mọ pe o nidii: ara ẹni bẹẹ kò dá ati pe nnkan kò rọgbọ; oun yoo kú ayafi bi o ba ri iranlọwọ gbà. Bẹẹ gẹgẹ ni o ri fun Onigbagbọ́. Ohun kan ti ṣẹlẹ bi eniyan kò bá dagba mọ́. Alaisan ni nipa ti ẹmi, nnkan kò si rọgbọ fun un. Irú ipò bayii yoo yọrisi ikú ayafi bi o ba kepe Ọlọrun fun iranwọ́.

Onigbagbọ́ wà fun Oluwa lojoojumọ. Jijẹ ọmọ-lẹyin Oluwa lọjọ Ọsẹ tabi ki a maa digba ṣe rere kò to rara. Ninu ẹ̀kọ́ yii a ti kọ́ ọ̀pọlọpọ ohun rere ti Onigbagbọ́ n ṣe lati inu iwe Paulu ati Peteru. Ki i ṣe pe eniyan n ṣe nnkan wọnyii ki o ba le di Onigbagbọ́. O n ṣe wọn nitori pe o jẹ́ Onigbagbọ́ ni. Ohun ti o wà niwaju rẹ̀ nigba gbogbo ninu èro rẹ̀ ni lati wu Ọlọrun ati lati ṣe ifẹ Rẹ̀. Nigba naa ni Oluwa ati gbogbo ayé yoo mọ̀ nipa igbesi-ayé rẹ̀ pe Onigbagbọ́ ni i ṣe.

## AWỌN IBEERE

1 Ta ni o kọ iwe Romu?
2 Ta ni a si kọ ọ si?
3 Bawo ni eniyan ṣe le jẹ ẹbọ aaye fun Ọlọrun?
4 Ki ni o maa n jẹ ki eniyan jẹ́ oloootọ si Ọlọrun?
5 Ki ni eniyan le maa ṣe lojojumọ lati le di alagbara nipa ti ẹmi?
6 Ọna wo ni a fi le mọ̀ pe Onigbagbọ́ ni eniyan i ṣe?
7 Ki ni iṣe si Onigbagbọ́ si ohun ti i ṣe buburu?
8 Bawo ni Onigbagbọ́ ti nilati ṣe si awọn ti o ṣe e ni iwọsi?
9 Ki ni isọdimimọ́ maa n ṣe fun eniyan?
10 Ki ni didagba ninu oore-ọfẹ jẹ́?